# OWO OLOPA TE AJ'OMOGBE ALABI WO'TIMOLE



*AWOGBA Omode fun Giri, Ete, Nika-nika, Orere, Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Oladunmore Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS.*

ELETI ỌFẸ

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

U. T. C.
SERVES
YOU
WELL

VOL. No. VIII 479. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, AUGUST, 4, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)



Aworan Lamidi Alabi aji - ọmọ gbe ara ilu Ilọrin ti o ji odidi ọmọkunrin mẹta gbe nilu Eko, on l'owa larin awọn ọlọpa to f'oju pamọ yen.

## Owo Olopa Te Aj'omogbe, Lamidi Alabi Wo'timole

Ohun to ṣẹlẹ nilu Eko ni ọjọ Monday ọsẹ yi jẹ ohun ti Ọlọrun Ọba ninu anu Rẹ tu aṣiri na fun aiye ri, bibẹkọ, gẹgẹbi a ti ma ngbọ wipe ọmọ sọnu l'orekore ti o jẹ wipe bi ọmọ mẹwa ba di awati, boya ni nwọn le pada ri meji ninu wọn ni ọrọ iba jẹ.

Lamidi Alabi, ara ilu Ilọrin, ti o to ọmọ Ọgbọn ọdun l'ọjọ ori rẹ ni ẹniti ọwọ awọn Ọlọpa ọba te, ti o ji odidi awọn ọdọmọde'kunrin mẹta ti o si kan awọn ọmọ mẹtẹta na mọnu apoti nla kan ni ireti ati gbe wọn lọ.

(Wo yoku loju ewe keji)





Aworan awọn ọmọ ti Lamidi Alabi ara ilu Ilọrin ji gbe ti o kan mọnu apoti niwọnyi. Lati ọwọ osi, Musibau Amusa, Babatunde Afoke ati Ganiyu Musitafa. Gbogbo awọn ọmọ na jẹ ọmọ ile kanna ni No. 9 ati 11 Toguwa Street, l'Eko.

THE NATIONAL BANK

Of Nigeria Limited.

Ile Ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ onisowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
87, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.

## Owo Olopa Te AJ'OMOGBE Lamidi Alabi WO'TIMOLE

(O bere lati oju ewe kini)

ASIRI TU, WOMPARI RAN'JU TOTO.

Obinrin kan ri o wa nitosi Ile-iyagbẹ Ita-Ẹlẹiyẹ ti o gbọ igbe ọmọ kekere, bi o ti sunmọ ẹhin Ile-iyagbẹ na ni o ri Apoti nla kan ti ọkunrin gbọngbọnrọn kan duro ti, o si ngbọ ti ọmọ nke ninu Apoti na, o bere lọwọ Ọkunrin na wipe kilo ṣe ti o fi ko awọn ọmọ sinu apoti yi? baba olomọ yi si jajumọ wipe, kuro nibẹ! ma ba tirẹ lọ.

Ni obinrin na ba bọ s'ode, l'o tẹdi mọlẹ ti o si ke pe ọlọpa, were-were ọlọpa kan ti de, nwọn si ba awọn ọmọkunrin mẹta ninu Apoti na. Nigbati nwọn mu baba Ilọrin ati apoti de Ita Tinubu nisọ awọn ọlọpa, ki o wa wo ero ti o nrọ gidi-gidi lati fi oju ri ọmọkunrin Aj'ọmọgbe na.

Ki a ma fa ọrọ gun mọ nwọn mu Lamidi Alabi elenmọ de iwaju Adajọ ọgbẹni J. A. Cole ni Kotu Sant Anna ni ọjọ Tuesday ọsẹ yi, adajọ fi ẹjọ rẹ si ọjọ kan dgun osu yi.

A gbọ wipe awọn ọmọ ti o sọnu nilu Eko ninu ọdun yi to ẹdẹgbẹta.

Ṣe bẹẹ ni nwọn gbe odidi ọmọ lọ nilu Ẹfọn Alaye ti o jẹ wipe nigbati ijọba wadi lọ, wadi bọ nṣe ni nwọn gbe ọmọ na lọ ṣe ogun.

Bakanna ni nile Ifẹ Omode ti o nlọ silewe ni Mọdakẹke, ti nwọn lọ da lọna, ti nwọn si lu pa nitori ki nwọn le fi irun ori rẹ ṣe e bo.

Ki Ọlọrun to aṣiri awọn ika eniyan na fun wa ri.— Amin.

## A Nrin Nile, Inu mbi Elesin

Nigbati, nilu Eko, ọmọkunrin kan wa ti a npe ni Agẹ'sinko'le, Ọkunrin na ni ẹsin kekere kan ti o npe ni Agodongbo, bi yio ba lo si oko, yio g'ẹsin, bi o nlọ si odo, yio g'ẹsin, bi o nlọ ra ata lọja yio g'ẹsin, bi o nlọ ra ọpọ, bi o nlọ pọn'mi, yio gẹsin. Idi eyi ni ni awọn se npe e ni Agun-ẹsin ko-ila. Ọkunrin kan si tun mbẹ ọwọ lasiko na ti a npe ni Ọmọ-Onilẹ-tẹ ẹ jẹjẹ. Bi ọkunrin yi ba nlọ si ode, yio fi gọfu ṣe ọsọ ọwọ ati igba aiya, bi o ba nrin lọ o fẹrẹ le gba odidi wakati kan tan ki o to rin ẹsẹ mefa ja. Gbogbo eniti o ba pade rẹ, yio ma kii bayi wipe, Kai! Ọmọ onilẹ-tẹ ẹ jẹjẹ, Ajeji nte e giri-giri, Tambata ko ṣubu.

Ag'ẹsin-ko'la ngbe adugbo kan ti ko jina si ọja Ereko atijọ bakanna nile Ọmọ-onilẹtẹ ẹ jẹjẹ ko jina pelu. Lọjọ kan awọn mejeji yi jijọ pade larin ọja Eroko, gbogbo enia nki Ọmọ-Onilẹ-tẹ -jẹjẹ mẹsan, mẹwa, eyi mu ki inu bi Ag'ẹsin ko'la o fi oju abuku wo o, o si gba ẹṣin rẹ ko ja lọ.

Sugbọn nigbati orin bi iwọn ogoji ẹsẹ inu rẹ tunbọ ru s'oke, o ja apẹrẹ rẹ silẹ, o fa ijanu ẹsin rẹ ẹ le, o di Kutupa kutupa, kutupa, nigbati awọn enia gburo pe ẹṣin mbọwa nwọn yara kuro lọna. Ọmọ-Onilẹ-tẹẹ jẹjẹ tunra rẹ ya loju ọna. Nigbati Ag'ẹsin-ko'la ṣe ifẹsu rẹ tan ti o si ti lọ, nigbana ni Ọmọ-Onilẹ rẹrin, o si wipe, "A ba le ma rin nilẹ, ki inu si ma bi ẹlẹṣin ndan"?.

## O Mase O, Ofo Se Bodilon

Ọmọ Gomina wa atijọ ti a npe ni T.C. Bourdillon jẹ ọkan ninu awọn ẹgbẹ kan ti a ba ma pe ni Agun'ke. Iṣẹ awọn ẹgbẹ na ni wipe, lati ma gun awọn oke giga gbogbo ti o mbẹ l'ode aiye.

Awọn ẹgbẹ Agun-Oke yi ni ẹgbẹ ti o de gongo ori oke Everest ni ọdun 1953, ọmọ Gomina yi jẹ ọkan ninu won.

Ṣugbọn awọn ẹgbẹ yi tun dide lati lọ gun oke giga miran, ninu eyi ni a gbọ pe ọmọ Gomina yi ja fọlẹ ti ọlọjọ fi de.

Ki Ọlọrun fi Ọrun kẹ.

## Yanmu-yanmu Lo Nk'o Aisan Ba Enia

BRAZZAVILLE. Awọn ẹgbẹ kan ti a npe ni World Health Organisation ti gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na jẹ Ogedegede awọn ọjọgbọn ninu iṣẹ iṣegun. Awọn lo sọrọ yi wipe diẹ ninu awọn arun to buru nilẹ Africa ti aisan rẹ si le pupọ ju jẹ eyiti o jẹ wipe nipa bibujẹ kokoro Lo fa iru arun bi iwọayi:- Iba ọrẹrẹ, Iba Pọnju-pọnju Ifo, Petẹlẹ, Jakutẹ, Igbẹ ọrin.

Iru awọn kokoro to nṣe onikọ iru arun wọnyi ni kokoro yanmu-yanmu, Eṣinṣin, Idun, Ina ori ati Ina aṣọ.

Iru egbogi kan ti a nlo lati fi pa wọn ti a npe ni D.D.T. nikọnṣọṣọ ni o kapa awọn kokoro na.

## Obe ati Iso L'agbedu ENIA

Tokyo. Orişirişi enimọ li a nri nile aiye, ni awọn nkan iyanu ni ọkan-kojọ'kan.

Nilu yi, laipẹ ase ijọba Japan ni ọkunrin kan ti o ti nya igbẹ ẹlẹjẹ, ati ti ara rẹ nṣe wọnra-wọnran ṣalaisi.

Awọn Dokita fẹ mọ iru arun ti o pa ọkunrin na, nigbati nwọn la agbẹdu rẹ, iwọnyi ni awọn nkan ti nwọn ri ko jade ninu rẹ na.

1. Burọşi (Brush) ti a fi nfọ ehin merindi-lọgọta (56)
2. Iṣo ti a fi nkan igi, mọkanlelogun. (21)
3. Ọbẹ ifari mẹtala (13)
4. Pako ti a nrun ogun (20)
5. Fountain pen,
6. Lẹdi (Lead)
7. ati awọn nkan lile miran. Ode gbangba ni ọkunrin na kusi. Awọn ẹbi rẹ sọ pe, bi o ti ma ngbe wọn mi niyẹn lati gba ti o tita tẹtẹ ti ko si jẹ.

## Ogun Nrorodede Lori Ito Suesi Nile Egypt

Lori ọrọ Itọ odo kan ti nwọn npe ni Suez Canal to wa nilu Egypt ti alakoso ilu na kede wipe awọn yọwọ-yọsẹ awọn ilu miran kuro ninu ohun to ba kan Itọ odo na ni ohun ti o mu ilu awọn Oyinbo Gẹsi, Faranse Amẹrika ati Itali fagbọn'mu ja, ti ọrọ na nfẹ da ijọgbọn silẹ nisisiyi.



Ọba Obinrin Elezabeth Keji ti ilu Gẹsi ti t'ọwọ bọ iwe ikede wipe ki awọn enia rẹ ma a ṣe akojọ awọn ọmọ-ogun silẹ de aibamọ.

Ki Olodumare majẹ ki a tun ri ogun o,

## Kilo Ny'apari Lori Ti O Mmokun Lodo

Niwọn ọdun 1915 nigbati Ijọba Eko nfẹ kọ Bode ibiti awọn ọkọ oyinbo yio ma gunlẹ si nwọn fi ọkọ kan ti o ngbẹ'do tu erupẹ sinu adagun omi ọsa ti nwọn ge, awọn wa ko awọn ẹlẹwọn wa lati ma ru yẹpẹ nibẹ.

Bi awọn ẹlẹwọn nwọnyi ba nṣiṣẹ lọwọ, awọn enia ti o nṣiṣẹ ati awọn ti o nkọja lọ yio ma wo wọn, gẹgẹbi aṣa awọn ẹlẹwọn bi nwọn ba nṣe iṣẹ lọwọ, nwọn o ma kọrin, nwọn o si ma jo.

Lọjọ na lọhun, nigbati, iṣẹ ka ẹlẹwọn kan lara, enia ṣa ṣoro darukọ, o ju apẹrẹ rẹ ofifo soke, o si tun gan a, bẹrẹ si nkọrin bayi wipe :

Eni a to timama
Eni a ro timama

Awọn enia to ri ẹlẹwọn na ti o nkọrin bayi bu s'ẹrin. ọrọ yi na lo di owe ti nwọn npa titi di oni wipe, "Kili ohun ti o nya ẹlẹwọn lori ti o de Bode, t'o ju apẹrẹ s'oke ti o nkọrin pe, Eni a ro timama.

## Ojo Ironu piwada ni Ilesha

ILESHA. A gbọ wipe ọkan ninu awọn Woli Aladura lo riran ti o si sọ asọtẹlẹ si ilu Ilesha wipe, nitori ti iwa wọn buru jọjọ ti aiṣedede wọn si bo wọn mọlẹ, Ọlọrun yio fi ajakalẹ arun bẹ ilu na wọ.

Ẹru ba awọn ara ilu na, nwọn si wariri, Ọba Ilesha si ṣe ikede ọjọ Ironupiwada. L'ọjọ ironupiwada da na, igba ko lu igba, awọ ko lura wọn, gbogbo ṣọbu lo ti, ẹnikan ko patẹ, ẹnikan ko si taja, nwọn si gbawẹ pẹlu. Ọlọrun ko gbadura nyin o, Ọmọ Ọwa.

## Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe

## Nwon Nwa Ilu Kan To Ti Pare Lo

PETERMARISBURG. Awọn opitan a ma fi ṣo itan pe nigba gbogbo wipe, ninu aṣalẹ kan ti a npe ni Aṣalẹ Kalahari ni iha gusu ilẹ Afrika ilu nla kan ti wa ti Ọlọrun bajaka rẹ ti enia ati gbogbo ohun ti o mbẹ ninu rẹ lo ri si abẹ ilẹ.

Lasiko kan awọn ẹgbẹ kan dide lati lọ wa eyiti o ṣeku ninu ilu ti o parun na, ṣugbọn pabo ni nwọn ko ri i.

Nisisiyi lodun 1957 awọn ẹgbẹ kan nfẹ jade lọ lati lọ ṣe ofintoto ibiti iyoku ilu to parun na gbe wa. Ilu ti nwọn nwa lọ ni eyiti awọn Oyinbo npe ni "The Lost City"

## Okunrin kan pania tan o d'a fe'ri.

SICILY. Irohin kan wa wipe Ọkunrin kan gba'na jẹ nigbati o gbọ wipe iyawo rẹ lọ ṣe iṣekuṣe.

Kini Ọkunrin na gbọ bayi si lo ba tutọ s'oke ti o si foju gba a, ori rẹ gbona, o o yi wọle, egbo ibọn, o yin ọkan fun iyawo rẹ, otun pa obinrin kan si keji, ẹnikẹta to yin ibọn si, agbọn se ta.

Ha! ha! ha! o yinbọn pania, nibiti nwọn nfẹ ra mu, bẹni o di aferi mọ wọn lọwọ. Nwọn ṣi nwa Ọkunrin apania na nwọn koiti mọ ibiti o ha si titi di isisiyi.




Awon t'o nlo wo ran ere esin feran siga Capstan, orun nwon si dara pupo.





FUN

Agbara Eje ati

Agbara Okunrin

HOMMEL'S

HÆMATOGEN

Hommels Haemtogen jẹ egbogi ti a ṣe ninu ẹjẹ akọ Malu, yio fi ẹjẹ rere tun ara rẹ ṣe, ati irin ti yio fun enia lagbara bi akọ Malu.

O mbẹ ninu igo fun tita yika Ṣọbu ilẹ Nigeria.

Fun Agbara iṣẹ Fọsan,
Fun ilera lẹhin iṣẹ ati ere ṣiṣe.



Bere Lodo Asoju wa—
ALBAN PHARMACY LIMITED,
2, Victoria Street, P. O. Box 461,
Lagos - Nigeria.

# ELETI QFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJQ
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
28, Kesoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. VIII. NO. 479, LAGOS, SATURDAY AUG 4., 1956.


## Iberu Olorun Ni Ipilese Ogbon

Gbolohun akọle oke wosika wa yi ni a fi ṣe ẹsin aṣaro ọrọ wa ọsẹ yi, l'ori iṣẹlẹ to ṣẹ nilu Eko wa yi ni ọjọ Monday ọsẹ yi ti iṣe ọgbọn'jọ oṣu July, 1956, ti gende ọkunrin kan lọ ji ọmọde'kunrin mẹta gbe l'ọna Ita - Eleiye ti o si kan awọn ọmọ na mọnu apoti laiko bikita fun inira ti oru yio ko ba wọn ninu apoti na.

Irufẹ iwa ọdaju bawọnyi fi han wa wipe aiko ni ibẹru Ọlọrun l'ọkan ni ohun ti o nmu enia hu iwa buburu gbogbo, bi iwa ika, iwa ole, iwa ipania ati iwa ki enia ji ọmọ - ọlọmọ gbe yala ni ero ati ta sọdi owo tabi lati fi ṣe egbogi ti nwọn fi ndi olowo arakuyamu lai ṣiṣẹ, (gẹgẹbi agbọsọ ọrọ ti a ma ngbọ) ko si ohun meji ti o nfi iru ero agadamaṣa bawọnyi sinu ọkan ọmọ enia ju aiko ni ibẹru Ọlọrun lọ.

Nitorina ni Iwe Mimọ ṣe fi kọwa wipe "Ibẹru Ọlọrun ni ipilẹṣe ọgbọn" ẹniti ko ba ni ibẹru Ọlọrun l'ọkan rẹ, ko si iṣẹ aidara ti ẹnibẹ ko le ṣe, nitoripe bi enia ba ni ibẹru Olorun, Ẹlẹdẹ Ọrun ati Aiye, Ọba arinu-r'ode, Olumọ'kan, ko ni saba ma duro nibiti iwa buburu ba wa d'epo ki o wa fi ọwọ ararẹ ṣe iṣẹ buburu.

E jẹki gbogbo wa kọ ẹkọ lati ni ibẹru Ọlọrun l'ọkan wa nitoripe bi enia ba ṣe aidara kan ni ikọkọ pẹlu ero wipe ẹnikan ko ri on, bi Ọba aiye ko ri ọ, t'ọrun nwo ọ.

IBẸRU ỌLỌRUN NI IPILẸṢẸ OGBỌN

## Idibo Ilu Aganyin

Ibo ti nwọn di lati fi yan awọn enia sinu igbimọ Aṣoju ilu Aganyin Gold Coast, bọsi ọwọ awọn ẹgbẹ Convention People's Party ti ijọba ti wa lọwọ wọn tẹlẹ. Awọn ẹgbẹ yi ni Alakoso ijọba Gold Coast jẹ Akonijẹ wọn ti a npe oruko rẹ Ọgbẹni Kwameh Nkrumah, on na tun ni akoso ijọba ilu Aganyin tun bọsi lọwọ.

Gẹgẹbi ibo ti nwọn di na ti lọ niyi:-

Ẹgbẹ Convention Peoples Party-71
„ National Liberation Movement-15
„ Northern People's Party-12
„ Togoland Congress-2
„ Muslim Asso: Party-1
„ Federation of Youth Movement-1
Awọn ti oda duro — 2

enia mejidinlogoji (38) ni awọn ẹgbẹ Convention People's Party fi gbe apapọ gbogbo wọn.

A ki Ọgbẹni Nkrumah ku ori're.

## Egbe N. C. N. C. mbi rehin

ISẸYIN. Ẹgbẹ afenifẹre ndagba siwaju nitoripe, lori ẹtọ ati Ododo ni nwọn duro le, Ọrọ Ọlọrun si ti sọ wipe Ododo lo ngbe orilẹ ede leke. Sugbọn rikiṣi, irọ, ati mọnafiki okun wọn ko ni pẹ ki o to ja.

Nilu Iṣeyin ni a gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ N. C. N. C. to mbẹ nilu na njoro ku lọkokan pẹlupẹlu lati gba ti Gbadegẹsin ti gori oye Ọba lọyọ ni gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ti bẹrẹ si fori mọkunkun kuro ti nwọn si nwa fori sabẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre.

O to iwọn ọdunrun ninu ẹgbẹ N. C. N. C. ti o wa fori s'abẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre nisisiyi.

## Ile titun fun awon osise

Ọga agba nibi iṣẹ awọn igbimọ L. E. D. B. sọ pe, igbimọ ti o nfi adọta ọkẹ pọun kọle si Suru Lere fun awọn Oṣiṣẹ wipe ati gba iwọn ọgọrun oruko awọn Oṣiṣẹ ti a o ko lọ sibẹ silẹ.

A nṣe eto lọwọ fun awọn ti ati gba oruko pe Igbakeji ọga agba yio ri wọn ni pa alafia ara wọn. Awọn ti o mbọ na ni ẹgbẹ Alanu Alagbelebu pupa.

Yio to ọsẹ mẹta ki nwọn to bẹrẹ si ko si awọn ile na.

## Moto Akero de Suru Lere

Ọga agba nibi iṣẹ awọn igbimọ L. E. D. B sọ wipe,on ti ṣe eto pẹlu awọn igbimọ Lagos Town Council ati awọn ẹgbẹ Oni-mọto Akero wipe ki nwọn ni Mọto kan pataki ti yio ma ko awọn enia lọ si Surulere ni bi ile titun. Mọto na yio bẹrẹ si rin lati ọjọ Monday 30th oṣu July 1956.

## Awon onigboiya aiye lo pade oba

LONDON. Nitori ki a ba le ṣe ajọdun ọgọrun ọdun ti ọba obinrin Victoria da oye V. C. eyiti a ma fifun awọn alakikanju l'oju ogun tabi ninu okan miran silẹ, ọba obinrin ilu Gẹsi ranṣẹ si gbogbo awọn enia ti a ti fi iru oye yi da l'ọla, kakiri gbogbo ilẹ agbaiye wipe ki nwọn pade on nilu London fun ajọdun.

Nigbati ẹsẹ gbogbo wọn pe si Ibikan ti a npe ni Hyde Park tan ni ọba obinrin Elizabeth Keji wa dide, o sọrọ bayi wipe:-

Awa Gẹsi ko fẹran ita'jẹ silẹ tabi ija ogun, sugbọn nigbakigba ti ogun ba si dide si wa, awọn ọkunrin ogun wa mbẹ, ti nwọn si ti ṣe gudugudu meje niṣiwaju eyiti o sọ wọn di ẹni Ibọwọfun kakiri aiye, ti ẹru wọn si mba awọn ọta wa. Ni gbogbo ọgọrun ọdun ti a ti da iru oye yi silẹ, Igboiya wọn si mbẹ sibẹ-sibẹ.

Lẹhin eyi ni awọn ju ilu si gbogbo awọn ogboiya na si jo koja niwaju ọba.

## Alhadji Maito wole

ILỌRIN. Alhadji Maito ti o nṣe Baba-ẹgbẹ Talaka parapọ dibo ni adugbo Alanamu ni Ilọrin

Iye awọn enia to dibo fun u jẹ mẹrindinladọrin iye awọn enia ti o wa dibo fun alatako rẹ jẹ mejidinlọgbọn Afẹnifẹre T. Parapọ 66
Ẹgbẹ N. P. C. 28

Ninu gbogbo ibo ti nwọn ti ndi na.
Afẹnifẹre lẹ 7.
Hausa N. P. C. 5.


## ABOKI



JẸ AWOGBARUN to LOKIKI KA ILẸ ENIA DUDU.
AJEBIDAN ni fun IKỌ, LAKUREGBE, IWORA, AKOKORO, SOBIA, AKANDUN, JEDIJEDI, etc.
KOṢEFEKU ni GBOGBONṢE yi jẹ fun GBOGBO ILE nitorina RA IGO kan LONI Lọdọ:-

IBUKUN - OLU MEDICINE STORES,
Amunigun Street, Box 245, Phone 189x, IBADAN
E 21, Sabongeri, ZARIA, X 5, Central Market, Box 2205,
Kumasi, Gold Coast.

## Kere o!

A ti ni orisirisi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road, Lagos

## Irora Ni Orikerike Ati Isan Ara

BOYA ARUN IGBAROKO LOFA



Ise ti KIDINRIN tabi olo - inu nṣe ni lati ko gbogbo idọti ti o mbẹ ni ara danu. Bi awọn Kindinrin nwọnyi ko ba ṣiṣe daradara awọn idọti ara na yio ma po si, yio si wa di irora fun enia ni orikerike ninu ara.

Ọna ti a le gba fi ba gbogbo arun yi ja ni wipe ki a ṣe iranlọwọ fun Kidinrin lati ṣiṣẹ rẹ egbogi ti a npe ni DE WITT'S yi lo le ṣiṣẹ na.

Nitori iru arun bayi ni a ṣeṣe egbogi na o si jẹ atura o si nfọ inu enia mọ opa jijẹ ki Kidinrin bere ise.

A ti dan egbogi DE WITT'S yi wo a si ri wipe o dara, Kakiri gbogbo agbaiye ni a nta Ọpọlọpọ iwe ni a ti ri gba lati ọdọ awọn ti arun yi mba ja, ti awọn si ti ri iwosan kiakia.

Kini nda ọ duro ti iwọ ko danwo fun irora tirẹ lọ si ṣọbu egbogi lọ ra ọkan wo.

Egbogi DE WITT'S dara fun Ẹhin didun, Irora Orike, Lakuregbe Igbaroko ati arun Isan ara.

Obun ti o dawa loju nipe egbogi DE WITT'S yi jẹ uyiti a ṣe tonitoni gbogbo egbogi rẹ l'o si dara.




**DE WITT'S PILLS**

**for Kidney and Bladder Troubles**






**ARADAN NERVIGORA**

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ti a rẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ didu, iṣokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun, ailokun ninu, ati irufẹ arun bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹṣẹ kun bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d e.g. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores** 112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute - Metta. Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.





**Nje nwon fe gba bolu lose yi? fi egbogi ajebidan pa awon ibiti o ndun o**

**ELECTRIC Balm**




## Ọmọ Ife Eko

Gẹgẹbi ẹdun ọkan mi ati gẹgẹbi mo ti ṣe ri iṣesi orilẹ ede miran ti o mbẹ ni igboro Eko, eyi mu mi kesi gbogbo ẹnyin arọmọdọmọ ọmọ Ile-Ifẹ ti o mbẹ ninu Eko ati agbegbe rẹ lati ronu piwada kuro ninu aikobikita fun ara wa, tabi aiko jumọ ṣe pọ wa, eyiti ẹnyin, papa mọ daju wipe, "Karin k'a pọ yiyẹ lo nyeni", iru irẹpọ ti o ti wa larin awọn Iya ati Baba wa ti ẹnikẹni fi mọ wọn ni ọmọ Ile-Ifẹ ninu igboro Eko kanna yi.

Ninu ilu Eko loni, Beriberi ṣa ara wọn jọ, bẹni Kukuruku ṣa ara wọn jọ ki a ma tilẹ tun sọ awọn yoku mọ.

Bi ẹ ba fi oju inu wo o, tabi, bi ẹ ba ro o ni a ro jinlẹ, ki iṣe ọmọ Ile-Ifẹ ni koni ni akọjọ kan pataki l'arin ilu Eko.

Lati igba iwaṣẹ ni Ọlọrun ti ṣe ilu Ile-Ifẹ ni Olori fun gbogbo orilẹ ede kede, a ni, titi di oni oloni, Olori na ko ti kuro lọwọ Ifẹ, eyiti ẹnyin na mọ daju wipe, kosi orilẹ ede kan ti o jẹ da hẹ ẹ, tabi, ki nwọn pa ẹgan ilu Ile-Ifẹ, eyi ko ha to ohun ti awa ọmọ onibiniran ti a bi ninu ilu na ki a pa ara wa pọ ki a tubọ gbe iyi ati ogo ilẹ "MỌREMI" na ga ju bi nwọn ti npe lọ?

Nigba aiye Ologbe Ọgbẹni Ojo Olufiede, ẹniti a mọ adape orukọ rẹ ni "Saji Ojo", mo ṣe iranti wipe, gbogbo ọmọ Ile-Ifẹ ti Eko ati agbegbe rẹ ni nwọn ma nlọ pe sinu ile rẹ ni Idi-Oro, ti nwọn si nji roro lori ire ara wọn ati idagba soke ilu Ile-Ifẹ, fun ajọ ṣepọ wọn igbana, ẹnikẹni lo mọ wipe, ọmọ Ile-Ifẹ mbẹ ninu Eko.

Lẹhin iku Ologbe ọgbẹni Olufiede, ni Ologbe Ọgbẹni Willie Fagbọ, tun dide gẹgẹbi alakojọ, eyiti mo ri wipe, akojọ na ko iti fi ẹsẹ mulẹ ki ọlọjọ to de ba.

Ẹ dakun, mo gba ẹnyin agbalagba ọmọ Ile-Ifẹ ti o tun ku ni igboro Eko loni ni iyanju, ẹ dide fun isowọpọ wa, itiju nla ni eyi jẹ, ko dara rara lati ri wipe, bi ọmọ Ile-Ifẹ ti pọ to l'eko ki nwọn ma ni akojọ kan pataki. "Wiwọn epo tabi, aiko ri owo ra a" a ko gbajumọ to ni tabi a ko lowo lọwọ to?.

Ẹ jeki a lọ pa ẹgan, tabi Ọmọ-tani-yeni, aiye ijọun ti si apakan, ẹ jẹki a fun okun Ṣhokoto ati okun Tobi wa s'oke ki a parapọ mọ Akojọ tuntun ti awọn Iya wa Wulemọtu Lagunna ati Asimọwu Bandefẹ ṣẹṣẹ da silẹ ni agbo ile Ọgbẹni Rufai Giwa Awoyejọ ni Ita Alagba l'eko, fun Ire ara wa ati idagba s'oke ilẹ Odudua, eyiti yio jẹ abọwaba fun awọn arọmọdọmọ wa lẹhin ọla.

Ori ni Ọlọrun ṣe wa, ẹma ṣe jẹki a fi iwa aiko ka ara wa si inkankan rẹ ara wa silẹ ẹ dide, ẹ jẹki a gbe ọla Odudua ati Mọremi ga larin ilu Eko.

Oluwa koni rẹ ẹnikọ-ọkan wa silẹ.

Olotu, mo dupẹ fun aye ti o gba mi ninu Iwe-irohin rẹ. Ọna ti aṣiri rẹ ngba ti o fi mbo, Oluwa koni di ọna na mọ ọ.

ASẸ.

Ọmọ - Adumila
Eko.

## Eran bi meta, oluwa re bi meta

ENUGU. Obinrin Ibo kan l'oyun, ẹran ewurẹ rẹ papaa ni oyun. Bi ewurẹ na ti mbimọ lowurọ, oluwa rẹ si bimọ ni aṣalẹ.

Ohun ti o wa jẹ ti iyanu nibẹ ni wipe, ọmọ mẹta ni ewurẹ na bi l'ẹkanṣoṣo, ibẹta si ni oluwa rẹ papaa bi.

Ọmọ ẹran mẹta yi ati ọmọ enia mẹta, ndagba siwaju, ko si ohun ti o ṣe wọn.

Ijọba Ila-Orun ti ṣe ofin nitori ki awọn enia maṣe ko ọmọ ibeji tabi ibẹta danu mọ, nwọn o fun iya ibe'ta na ni ọgbọn pọun lati fi ṣe itọju awọn ọmọ na.

Asọrọ aila lo pa Elempe iṣiwaju to wipe igba wuwo ju awo lọ. Iya to bi ọmọ enia mẹta ni yio gba owo, ẹran ko ni gba rara.

# Agbo meji ki i mumi ni kotokan

LONDON. Nigbati ogbodiyan ilu Cyprus se nię peleke, ni Gomina ilu na ti a npe ni Ogbeni Harding ba to si eto wipe, ni won igbati Alufa Bishop Makarios ba si mbę larin awon janduku na ko le si alafia ni ilu, ayafi ki a wa Alufa na lo kuro larin won.

Eyi ni idi re ti ijoba Cyprus fi wa Alufa na lo kuro nilu si erekusu Seycheles larin agbami okun rere. Sugbon lati igba ti nwon ti wa alufa na lo yi, ko si alafia ninu ilu, nse ni ijogbon tunbo npeleke ti ofo si nselę firi-firi. Gomina ranse pe awon olopa awon olopa lati wa petu si oro na, Pabo! O tun ranse pe Soja, Pabo!. Awon enia na tilę wa rari nisisiyi wipe awon ko ko ika mo. Awon Tatamb'olu ati awon Griki ti wa gba'ra je. Iduro ko si, ibere ko si, fun eniti o gbe omori odo mi.

Awon igbimo ilu Oyinbo ti nwon ti nwoye gegeri nkan na ti nlo, bere si tako ara won. Ogbeni Atlee so fun awon igbimo nilu Oyinbo wipe, ijoba Cyprus se asise nipa wiwa ti nwon wa Alufa Makarios lo. Nitori na ki ijoba na lo gbe Alufa Makarios fo wa ti ilu oba fun oro ajoso. Ki o wa so fun wa ona wo ni yio gba ti alafia yio fi gbilę nilu Cyprus, bi nwon ha pa ilu Cyprus po mo ilę Griki.

# Owo Te Eniti O Mu Egbogi Wa Si Alafin

OYO. Irohin kan wa wipe, lasiko ti Alafin titun Otimadegun Ladigbolu Keji mbę lori aye ola re ninu Afin Oyo, ti gbogbo enia nwa l'okunrin ati l'obinrin ti nwon nkerufu fun oba titun na, beni Odomokunrin kan ti a npe ni Adedokun Apara, o je omo adugbo Apara l'Oyo o mbo wa kerufu fun oba, sugbon oba ti s'akiyesi re lati okere wa.

Oba na pase wipe, ki nwon wo okunrin ti o nla arin awon enia bowani, ki nwon mase jeki o dobalę fun on, ki nwon ramu.

Bi o ti nfę dobale, ni nwon ba ramu ni agbedemeji, nwon ranse si Olopa ki o wa mu okunrin na. Nigbati Olopa de, nwon bere si tu ara okunrin na wo, nwon ri ogun kan, ti nwon fi eje pa gbogbo ara re. nse ni gbogbo enia si se ha! Bi ko ba si opelope ti oba titun na, nse ni nwon iba lu u bolę.

Nwon bere wipe ki lo wa se ni Afin, o wipe, on ko wa se aidara, ijoye kan l'o ni ki on wa ki oba, ni awon Olopa ba mu odelesinrin okunrin na lo pamo.

•

Nigbogbo akoko yi, nse ni awon obinrin nwa si Oyo lati ilu Awe, Akinmorin, Igboho, Iganna, Okeho, Iseyin, Akinyele, Ojoo, Jobele, Iroko ati Ilora. Gbogbo awon obinrin na lo fi ara mo ti Alafin titun.

•

# Pasan Ti A Fi Na Iyale Mbe Loke Aja Fun Iyawo

Nighani nigbati iteao mbe larin awon omo eranko enia ko ri won paje nitori pe nse ni awon eranko aria papo, ode ti o ba si gbo-ju-gb'aiya lati pa okan ninu won awon eranko yoku ni yio pa ode na.

Lojo kan ara Olube ko da nitorina kole ba awon egbe re rinpo. Agemo bimo na simojo ku si owo omo na. Nigbati Olube ko le rin mo awon egbe re ko o sile.

Nigbati nwon rin bi ibuso kan Ajapa da gbogbo eranko duro o wi fun won pe Pasan ti a fi na iyalę o mbę loke aja fun iyawo. Nse ni ki e duro ka lowo ara Olube ti o eku lo yi ara wa ni; gbogbo won si ko. Nigbana ni Ajapa wipe be be a kari o.

Ode kan rin titi o kan Olube, o ta lofa o pa a o si gbe lo. Lati gba na wa enikan ko tun be Olube wo mo. Omo eranko to ba nse are awon yoku ko tun nduro de mo. Lati gbana ni owe ode ti bere si ma te eranko. Epe ajapa ti o se wipe "be-be akari o" ti bere si ja lori won.

# Omo ilu Sare se bebe nile Ijebu

IJEBU-ODE. Egbe awon omo Sare ti eka ilu Ijebu se ariuye wuye lasiko odun ileya to koja yi. lehin ti nwon kirun odun tan, malu merin ni nwon pa.

Ogoje ni awon eleyinju ege omo Sare ni obinrin ti o wa sibi ase na, awon okunrin si to odunrun enia Olori egbe omo Sare ni ogbeni Aremu Ofe, odidi malu kan ni o fun awon egbe yi. O'un Alaga ni ogbeni Ogun-omo-alapata, on na papaa tun fi odidi malu kan ta egbe lore.

Ogbeni Amodu Atuyagba omo ilu Sare na tun fun egbe na ni malu kan. Egbe na fi owo ara re ra malu kan.

Iyalode egbe awon obinrin ni iyafin Ajike iyawo Sarayi Sare, gbogbo ohun mimu ojo na dá ni o sona re. Apoti Bia mewa lo fun egbe ati igo Sitaotu Bia mejo pelu.

Omo Sare nse okan, eniti ko dun mo, kof'eni sole, omo Sare nse nkan.

Now Available

BUGLES, BEDSTEADS,
PAINTS, DISTEMPERS
SAFES Etc.

Just Write, Call Or
Phone 21372

IKORODU
TRADING
COMPANY

20/28 BALOGUN STREET
(P. O. BOX 395) LAGOS.
and NEW COURT ROAD,
IBADAN.

# Ijoba Edda dabo bo ibeji

EDDA- O ti je asa fun won ni ilu Edda ati kakiri nilę Ibo, bi enikan ba ti bi omo ibeji, yala ki nwon fi owo di awon omo mejeji ni imu pa tabi ki nwon pa eyiti o je okunrin ki nwon si fi eyiti o je obinrin silę.

Pelu-pelu, iya to bi awon omo na yio di eni ikorira larin ebi ati ojulumo re, enikan ko si ni ba so oro kan po mo.

Nisisiyi ijoba ilu Edda ti se ofin wipe, enikeni ti o ba fi oju buruku wo iya ibeji tabi ti o soro aidara si won, ijoba yio ba se ejo.

Ope ni fun Oluwa, diedie ni ilaju rere yio kari ilę Nigeria, ti gbogbo asa buburu ti aiye okuakuo yio ka'se kuro l'aiye.

No. 105.

Vacancy For Museum Technical Assistant

Applications are invited for the post of Museum Technical Assistant in the Antiquities Service.

Further particulars in Government Notice No. 811 published in Federation of Nigeria Official Gazette No. 31 dated 3rd of May, 1956. Application to Surveyor Antiquities, Nigerian Museum, Lagos. Closing date 31st August.

# Alafin titun gbade l'Oyo

ỌYỌ. Lọjọ Saturday oni yi ni Alafin tuntun, Bello Gbadegẹsin ọmọ Ladigbolu, ọba ana nlọ gb'ade ni Koso. Ẹṣin lo gun lọ si Koso. Ibẹ ni o ti ba Iy'aiye ati Alapanni, nitori awọn ni ẹniti o ni lati ṣe etutu fun l'ojubọ Ṣango, nitori ki ọba le pẹ laiye. Bi nwọn ba pari etutu na, Alafin yio bẹrẹ si de ade kekere kan ti a npe ni Orikogbofo.

Nigbati o ba di lọjọ Saturday to mbọwa 11th oṣu Aug 1956, Alafin yio tun lọ si Bara, nibi ọju orori Baba rẹ. Bi nwọn ba nlọ Ọba na yio duro kansẹ nibikan ti a npe ni ile Akaramako. Nibẹ ni a gbe kọ ile kekere kan si ti yio joko, ti yio si gba awọn Ọyọmisi lalejo ati awọn ijoye miran. Ọba si ni lati de Bara ni agogo mẹwa owuro. Ni Bara yi ni ọkan ninu awọn iranṣẹ ọba ti a npe ni Ọna-Onisẹ-Awo yio wa gbe ade le ọba titun na lori.

Arẹ-Gbaṣẹ ati awọn obinrin afin ọba ti a npe ni Iya-ile-isanyi yio wure fun ọba lẹhin igbade rẹ tan. Lati ihin lọ ni ase yio ti bẹrẹ, onjẹ yio ma se lori ina Onijo yio ma jo, awọn Ọmu yio mu ọti.

Alafin yio si pada si Afin lori ẹṣin, pẹlu ade lori pẹlu ilu ati ijo.

## Igbimo Ila Orun ta'porogan oro.

ENUGU. Lọjọ alamisi to kọja lọ yi ni igbimọ Ila-Orun (Ibo) ṣe ipade, kọ da, igi gangaran fẹrẹ gun ọrun loju. Nṣe ni ariwo nta ge-e-e, ti iwọ yio si ma gbọ iru ọrọ bawọnyi. "Ofin ni", "Aṣẹ ni" "Alafọwọra". "Onjjibiti" ti gbogbo ile igbimọ nho ge e.

Ohun to fa edekoyede na ni pe, Ọgbẹni Nnaji lọ sọ wipe iru iwa ti awọn apakeji nhu si Ijoba ko d ra rara nilẹ Ibo yi, on gba ni imọran wipe ki Ijọba maṣe ka wọn kun enia pataki mọ fun ohun ti nwọn ṣe ti nwọn fi binu jade kuro ninu Igbimọ.

Lori ọrọ yi ni Ọgbẹni Eyo dide, o wipe, eyiti awọn ṣe lọjọ na ni ojulowo ọna ti nwọn le gba nitoripe Ijọba ko fun wọn laye, lati ṣe alaye idi rẹ ti nwọn fi binu jade. O wipe ẹtọ ni ki awọn binu jade nigbati awọn ti gbe aṣiṣẹ Aṣiwaju wọn siwaju igbimọ, ti igbimọ na si ja wọn kulẹ, nṣe ni nwọn iba jẹki awa apakeji ṣe alaye ohun ti a ro ki nwọn to fi idi tẹ ọrọ wa mọlẹ pe, ma jẹki ouitirẹ ṣẹ e ni wa.

Nihin ni Dọkita Azikiwe papaa dide, o wipe on fẹ ki a ṣe akọsile awọn igbimọ ti o jẹ ulai bikata, ko si ni jẹ ohun to suuwọn bi ijọba ko ba nnani awọn apa keji yi. Nitoripe awa lo kọkọ fa awọn apa keji mọra ninu gbogbo ile igbimọ. Lẹhin eyi ni akọ ọrọ tabi ọrọ apara ti a kọ s'oke wa bẹrẹ.

UNDERSTANDING THE BIBLE

For free book making Clear the teaching of the Bible, write to: Bible Mission, (Room 16) 2, Grays Road, Slough, England.

Bi ọmọde ba ṣubu a wo iwaju Bi agbalagba ba ṣubu a boju wo ẹhin.

(Owe Yoruba)

## Asoju Ijoba Iwo Orun Nilu Oba



Oloye M. E. R. Okorodudu ti o nṣe aṣoju fun Ijọba Iwọ Orun ilẹ Nigeria nilu Oyinbo jẹ ọkan ninu awọn ẹniti a pe lati wa je ase nla kan ninu afin Ọba ilu Oyinbo,

Awọn enia to kun inu afin na lati fi onjẹ oju fun oju ati lati ma wo iru aṣọ ti awọn ti a pe si apejọ na yio wọ.

Oloye Okorodudu ati Iyawo rẹ mbẹ ninu awọn ẹniti awọn Oyinbo pagbo le lori ti nwọn nwo. Oloye na lo mbẹ lọwọ osi ti o fi lẹkẹ iyun kọrun, ti o si fi ọpa tẹlẹ duro legbẹ iyawo rẹ. E wo bi gbogbo enia ti pagbo yi wọn ka, ati agba ati ọmọde ti nwọn nwo aṣọ ti t'ọkọ t'aya lo ati imura wọn ni aṣa ti Ṣẹkiri.



Aworan yi niti Ọladipọ Okuwọbi, ọmọ ilẹ Nigeria wa nihin, on ni ẹniti ofo iwọn ẹsẹ mẹfa ati ẹsun marun on ni ẹniti o fo ga julọ nilẹ Oyinbo Gẹsi nisisiyi.

Ọladipọ Okuwọbi ni ẹ nwo nibiti o gbe nkọ Terry Dawes ọmọ ilẹ Gẹsi bi a ti nṣe yara sare.

